Appointmet vacant

1. Journey Man Printer
1. Advance Printer

Apply
Modupe Press
16 Bamgbose St
Lagos.

IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.

Notice

Ema polowo oja yin sinu Iwe Irohin Imole.

VOL. III No. 153 MONDAY JUNE 27 — JULY 3 1960 KOBO KAN (1d)

# Ijoba Apapo mu oro moto gbigba le fun awon osise won (Senior Service)

ILE IṢẸ ALAṢẸ TI O WA FUN ETO OṢIṢẸ TI FI IWE KAN SOWỌ RANṢẸ SI GBOGBO OLORI ILE IṢẸ IJỌBA APAPỌ NIPA ỌRỌ MỌTO FUN AWỌN TI O WA NI IPO GIGA (SENIOR SERVICE) NIBI IṢẸ APAPỌ.

Iwe yi sọ wipe Ijọba ntẹ mọ nileti pe iyani lowo ra mọto ti Ijọba nṣe fun awọn oṣiṣẹ ti o wa ni ipo giga gbọdọ tẹle awọn imọran wọnyi.

(A) Gbogbo awọn oṣiṣẹ ti o wa ni aye toga ju tabi ti iṣẹ wọn jẹ iṣẹ adaṣe ati awọn olori awọn ọlọpa ti aye wọn ti to Assistant Supritendent gbọdọ ya owo lati ra mọto.

(B) Awọn oṣiṣẹ ti owo wọn lọdun ti to ọgọrun mẹsan ati adọrun pọun o le mẹfa lọdun le bere ati yawo ki a dẹ ya wọn lati ra mọto.

(C) Gbogbo awọn ti owo wọn koti to oye ti a daruko loke yi ko tọ lati bere yiyawo ati ra mọto, ayafi ti iṣẹ tiwọn ba nṣe ba gba pe wọn gbọdọ ni mọto nikan ni a gba pe wọn gbọdọ ni mọto nikan ni a le daro ati ya wọn lowo lati ra mọto.

(d) Gbogbo awọn ti o ni mọto nisinyi lo le ma gba owo ti a ti nsan fun wọn nipa mọto na (basie allowance) gẹgẹbi ohun ti o wa ninu iwe aṣẹ Ijọba A. 14/1959. Ṣugbọn a ko ni fun wọn ni mọto mirau nigbati wọn ba tun bere fun omiran, g ẹ g ẹ b i ofin titun ti Ijọba mu silẹ.

## Obinrin kan bi omo Abami ni Abeokuta

ABẸOKUTA. Obinrin kan bi ọmọ abami kan ni ile iwosan nihin. Wakati mẹrinlelogun ti Obinrin yi bi ọmọ abami yi tan ni o lọ jẹ ipe Ọlọrun. Ọmọ ti Obinrin yi bi ni ori meji, oju meji, imu meji, ọrun meji, ati a r a kan.

Awọn Oṣiṣẹ ile iwosan ṣe iṣẹ aṣekara lati ripe Obinrin yi ye, ṣugbọn pabo ni gbogbo wahala wọn bọ si, abami ọmọ yi papa ti ku ki o to di wipe wọn gbe jade ninu iya rẹ. Oniṣegun ile iwosan Abẹokuta Dokita I.B. Ogun wa sọ fun onirohin wa kan pe ọjọ kẹta ti Obinrin ti o ku yi ti de ile iwosan ni o to ku atipe atigbana ni o ti nrọbi ti ko dẹ le bimọ. Dokita I. B. Ogun wa ṣe ikilọ pẹlu ẹbẹ fun awọn Obinrin pe wọn fi ti Ọbinrin yi kọgbọn ki wọn ye ile adahunṣe lọ, ko si ohun ti adahunṣe le ṣe ju wipe ki iru ohun ti o ṣẹlẹ si Obinrin ti o ku yi ṣẹlẹ si awọn ti o ba tu ntọ ọna ile adahunṣe lọ.

## Oro daru nibi ipade Ijoba Ibile IBADAN

IBADAN:- NI KETE TI O TI to wakati kan lẹhin igbati o yẹ ki ipade ọdọdun ti Ijọba Ibilẹ Ibadan nṣe bẹrẹ, ti a kosi ri pe ki awọn ọmọ asofin peju bi o ti yẹ ni Alaga ti a fẹ rọ loye Ọgbẹni Mojeed Agbaje, ba ṣe ikede wipe ipade ko ṣe e ṣe, atipe on yẹ ipade na si ọjọ imiran.

Ọgbẹni Agbaje wa ṣe alaye fun awọn oniwe Irohin ti o wa sibi ipade yi pe awọn ọmọ ẹgbẹ aṣofin Ijọba Ibilẹ ti o jẹ oloye ko wa sibi ipade yi, mọkandinlogun nitoripe wọn lọ ṣe ipade pẹlu awọn Ijoye miran nibiti Ọgbẹni Agbaje ko darukọ ni arin Ibadan.

Ọgbẹni Agbaje ẹniti awọn mẹrin ti o nṣẹnu fun Ibadan ni Ile Asofin ti Ipinlẹ Iwọ-Orun ṣe isọngbe rẹ, pẹlu awọn jankan-jankan ninu Ẹgbẹ N.C.NC. Ibadan ṣe igi lẹhin ọgba fun, wa gbe iwe kan jade ti awọn saraki N.C.N.C. fọwọ si pe awọn gba a gẹgẹbi Olori.

## Ewon odun kan fun Ambrose Osadebe.

Ọmọdekunrin fọlefọle kan ti orukọ rẹ njẹ AMBROSE OSADEBE, ti o ngbe 8, Nathan Road ni Surulere ni onidajọ kan ni Eko ju si ẹwọn ọdun kan gbako pẹlu iṣẹ aṣekara larin ọsẹ to koja. Ọdaran yi ni ẹniti awọn Ọlọpa fi ẹsun ole jija ati ile fifọ sun wipe o lọ fọ ile Ọkunrin kan ti orukọ rẹ njẹ Houman Francois ti ongbe 8, Thompson ni Ikoyi. ti o si ko gbogbo ohun alumọni rẹ laiku ikan, agbẹjọro Ọlọpa ti o wa ni idi ọrọ yi wifun Onidajọ wipe ni ọjọ Aje ti ṣe ogunjọ osu June ni ọdaran yi ẹniti o ti ngbe pọ pọlu ẹniti o ni ẹru ti o jiko yi mu mọto lọ si ile ọrẹ rẹ ti o si palẹ gbogbo ẹru rẹ mọ laiku abẹrẹ nigbati, onitọhun lọ si ibi iṣẹ awọn ohun alumọni ti ole yi ko ni ẹrọ gbohungbohun (Radio) ibusun, ọwọ, beba, apoti aṣọ, agogo, ati ohun iṣura ile gbogbo.

Awọn ọlọpa tun sọ fun adajọ wipe nigbati ole yi fi mọto ky ẹru yi, ile ọrẹ rẹ kan ni yaba ni o lọ ko pamọ si. Olọṣa yi ti o so fun Adajọ wipe on jẹbi ọrọ yi wi pẹlu pe, on pelu awọn ọrẹ on meji ni awọn jijọ parapọ lati fọ ile yi. Onidajọ ko gba ọrọ ole yi gbọ o si ju si ẹwọn ọdun kan gbako. A gbọ wipe ọdaran yi si ni iru ẹjọ fọlefọle kan bayi ni kọtu kan le Ebute Mẹtta eyi fi han gbangba pe onişẹ ibi ni ole, ọlọṣa yi.

# BA FURO MI SO TI-WO E LEGBE

Mo ki gbogbo ẹyin onkawe Irohin Imọle lọkunrin, lọmọde ati lagba jakejado ilẹ Na jiria. Ẹku tijọ o, ara o le bi. Ki nto bẹrẹ ọrọ, o yẹ ki nfi ara mi han yin Emi ni Bọrọkini alaṣaro, ọrọ gẹgẹbi o ti jẹ wipe ọrọ nbẹ lẹnu mi, ngo ṣa ba yin sọrọ lọsọsẹ, ṣe obẹ ki imi nikun agba. toto o sebi owe o ni ọsẹ yi, ngo sọrọ nipa awọn ọmọge wa, ati aṣọ Ba furọ mi sọ ti wọn nwọ kiri. Ni ọsẹ ti o mbọ ẹwẹ, ẹ o gbọ nipa awọn alarin fẹsẹ-sunlẹ, ati alairiṣẹ wọ ọmọde kunrin ti wọn ndaṣa igan ni ẹ Ibeṣe

Ọpọlọpọ ni ohun ti awọn ọmọge wa nṣe ti o jẹ wipe aṣeju ni wọn nṣe, se amọrewọ lo ba ẹkọ siẹ jẹ aṣọ ti o fo soke ti wọn nwọn yẹn kobur i ju fun ilẹ Afirika ti awa yi, nitori oru, sugbọn awọn ti wọn nwọ nkọ? iwa ibajẹ wọn pọ, o ju ti ẹgbere ti nṣọmiloju lọ. Ṣe ni aiye atijọ, aṣọ iro ni awọn iya nla wa ti ma nro, ṣugbọn nigbati awọn Oyinbo de, ti a si ko aṣa wọn, nṣe ni awọn ọmọge isesinyi ba aṣa na jẹ patapata.

Lati ọjọ ti oyinbo ti nwọ kaba, wọn ko fi ilẹkẹ Sidi ri, sugbọn awọn ọmọge ti wa ni ilẹ yi, wọn yio fi aṣọ inura (Towel) yi, ilẹkẹ bebe ki o le han daradara ninu kaba wọn. Njẹ eleyi ha ba oju mu ? Nigbati Oyinbo ṣe bata o ni ki a ma de mọ ẹsẹ fun imura ni, sugbọn nigbati awọn ọmọge wa ba ra bata tuntun lo ni, kaka ki wọn de okun rẹ mọ ẹsẹ, nṣe ni wọn yio tẹ okun rẹ mọle, eyini yio ma dun pabapaba bi wọn ba nrin, iwayi nba ilu jẹ Ohun pataki ti o mba awọn ọmọge wa ja ni wipe, wọn ko mọ imura amuyẹ, wọn ko mọ ohun ti o yẹ wọn, nigba miran ti wọn ba mura, wọn o gbe ọmọ Ọba fun Ọṣun, wọn yio fi dudu le pupa, wọn yio si gbode lọ. Kaba bonlo ti wọn nwọ, ti wọn npe ni ba furọ mi sọ yẹn, enia kukuru lo ba mu, ṣugbọn ni ilẹ yi, enia gigun lo nwọ, bi wọn ba wọ tan ẹsẹ wọn yio wa gun bi ẹsẹ agunfọn bi o ba si pe wọn lati fiye wọn wipe imura yi ku diẹ kiato bi wọn ba ma fesi ni wọn yi wipe ba furọmi sọ tiwọ ọ lẹgbẹ Bi o ba si tun sun mọ omugọ ara rẹ, yio wipe o le fakọ yọ ki o si ta panpa.

Kini itumọ aṣa kurumọ wọnyi ?. Ni idakọji bi awọn ṣe awọ awọn oyinbo funfun tobẹ ti o jẹ wipe bi wọn ba yọ lọkankan, wọn o dabi ẹlẹdẹ funfun ni wọn ṣe nfi ohun pupa kun ete wọn, eyiti ko ba si funfun pupọ, ko ni fi eyi ti o pupa kun ete rẹ sugbọn awọn aladugbo mi, wọn ko mọ orin eyi ti o yẹ wọn ẹlomiran ti o dudu yio lọku eyiti o pupa yoo, bi o ba yọ lọkankan yio dabi anjọnu inu igi, eni ti o si pupa ewe, yio lọ ku dudu, yio si dabi aja dudu, to gbe egungun hanu.

Ohun pataki ti mo fẹ sọ ni wipe ki awọn Obirin wa lọ kọ bi won ti se nmura. Aṣọ janpe ti wọn nwọ yẹn, enia kukuru lo yẹ, ki enia gigun ti ko lara ma ṣe wọ ki oma fi ara rẹ ṣe ẹlẹya. Imura asiko yẹ awọn Obinrin wa, sugbọn amorewọ wọn lo nba ẹko siẹ wonje.

Mo gba gbogbo awọn Ọmọge wa ati Ọdọmọkunrin ni imọran wipe ki wọn ma kọwe bere lọwọ mi iru imura ti o yẹ olukuluku enia ati oniruru igba. Ki ẹ si ma kọwe bere alaye lori ọrọ ti mo ba sọ.

---

## Itumo Ami Ara

Ti o ba ni ami ni ọmọ ika ẹsẹ, ki o to milari yio pẹ pupọ, iṣẹ pupọ ati ere diẹ ni ipin rẹ yio ma jẹ. Ti o ko ba si fẹ ki gbogbo ona rẹ ma ri rudurudu aṣọ funfun ni ki o saba ma wọ tabi buluu iṣẹkiṣẹ ti o ba si fẹ dawọ le ni ṣiṣe ọjọ Jimọ ni ki o jẹki o ma bọ si, ki o ba le ma ba asiki pade iwọ papa le bere itumọ Ami Ara rẹ lọwọ.

Onimimọ Irohin Imọlẹ
6, Ojo Road
Odunbọrẹ Mushin


# ṣile kan pere ra pakẹti 'ASPRO' TITUN yi




Pakẹti "ASPRO" titun yi wa fun tita nisisiyi nibikibi. Ṣile kan pere ni owo rira rẹ, kore ẹgbogi "ASPRO" mejila ni o wa ninu rẹ. Nisisiyi, ẹnikẹni le ni "ASPRO" ni ipamọ sọwọ lati ma a lo o ni gbara ti o ba ti ni OTUTU-IBA. O ko le mọ igbati OTUTU-IBA yio kolu ọ tabi ẹbi rẹ. Mura silẹ.
Ra pakẹti "ASPRO" titun oni ṣile kan loni!

# 'ASPRO' nda irora OTUTU-IBA DURO

# Imoran nipa Ife larin Okunrin ati Obinrin

IBERE

BOSE/ Mo ni ọkọ kan ọmuti gan an ni, ibaṣoye mo mọ wipe ọmuti ni nki ba ti fẹ, ohun ti o ti nba mi lọkan jẹ ni asiko ti iba fi ba mi lopọ, yio ti mẹmn yo gbsdi, a nbẹ Ọlọrun si ni mi ngo si fẹ ni ọkọ meji. Kini ki nṣe Bọsẹde? Emi ni Oyinda A.

IDAHUN

Oyinda A./ mo gba ni iyanju pe ki o ma farọ ṣere, ti o ba ba ọkọ rẹ sọrọ nigbati ko ba mu ọti yo pe ọti amuta ko dara, ti o si ṣe alaye fun pe ọmọ ni o nwa ni tirẹ ti ko ba gbọ kọọ silẹ ki o wa ọkọ atata fẹ nitoripe ọmọ laṣọ o Emi ni Bọsẹde

## Itumo Ala

JACOB ORIMADEGUN ILARO — Ala buburu ni eyi, iwọ ko ni pẹ gbọ iro buburu lati ọna jinjin rere, si ṣora o pa ija ija ki ẹmi ma ba lowọ rẹ bọ lasiko yi. Berẹ Ala rẹ lọwọ Joseph Iala 6, Ojo Rd Odusbore Mushin.

## Eja pipa nigba Owo Dile



ADA A PELU Afisọkan awọn ọmọde, owo rẹ kẹ Jẹ owo ti ọdọ le mu jade lati apo rẹ, aṣọ daradara yi ni ami o k u n bi ti bata ni orun, o si ni ọna lati arin rẹ de isale. ati ibiṣe aṣọ Londọnu kan ti o ni okiki ti oruko njẹ SAMBO FASHIONS, owu ẹgbọn ni wọn fi ṣe e lati ọwọ Bannister kọwe si Sambo Fushions, Samuẹl Sherman Ltd, 10c Hanover Square Londọnu W. I fun orisirisi aṣọ asiko to dara.

# Gbanjo Gbanjo O ma nlo

A O BERE SI ta ọja gbannjo wa lati ipari oṣu ti o yi (June 15—July 10 th 1960) a fi eyi kede si awọn Onibara wa wipe ki Olukuluku wa ra ọja tirẹ ki a to ye ta gbanjo wa.

APEJUWE ILE ITAWE WA

Ti o ba fẹ ba wa ra ọja, wọ Bus Oshodi ki o sọkalẹ ni "Mushin Bus Stop" ti o ba si sọkalẹ tan bere Wey Street, ti o ba si nba Wey Street lọ titi o fi pin ti o ba si de opin rẹ bere 6, Ojo Road, Oduaborẹ Mushin, Ọgba lapalapa ni odi Ojo Rd. loju, biri ti o ba ti yi si ehin ọgba lapa na ni iwọ yio ri Ojo Road.

AWỌN ỌJA KOṢEMANI GBANJO

Turari ẹyọnu awọn Agba ati Itaja—Aṣẹṣẹ tun ja ọgbọn turari yi ni, o le lo fun Adura tetedamilohun, Arisiki Onkapo awọn Ajẹ bi oba nlo bi ati ṣapejuwe rẹ oko ni mọ aita ọja, agbana ko si ni wọnu igba rẹ, turari ti a nta nisisiyi lagbara ni ilopo meji ju eyiti ati nta ri lọ gbiyanju lati raa ki o si le bọ lowọ Babalawo m'eran wa m'agutan wa, Iye owo rẹ 10/6d Idaji pangolo 5/6d Idanwo 3s.

IWE ILANA IFA, IYANRIN TITE, ETUTU ṢIṢE, IWOSAN ATI EGBOGI AJẸBIDAN

Awọn Agba ati Aiye ha ndamu rẹ bi? Awọn Babalawo ati Adahunṣe ha ti gb'ẹran aṣọ itẹlẹ ati owo rẹ bi? Agbaan ati aita ọja ha kọlu ọ bi? Abiku ha nyọ lẹnu bi? Tete yara ra ọkan ninu iwe yi nitoripe Ogbokangi Babalawo ni o ṣe iwe, agbara iwaṣẹ ti awọn Babanla wa fi nṣe Akin nbẹ nibẹ.

Ti o bi nlo iwe yi gẹgẹbi ati ṣapejuwe rẹ ọwọ Araiye ko ni kao, ohunkohun ti o ba si dawọtẹ rere ni yio ma fisi

IYE OWO 10/6d POSTAGE 1/- Afọṣe Isẹdalẹ Yoruba ati Psalm ajẹbidan 3/ Gbedegbeyọ Hausa 2/6d Lile ati agbara Psalm (Iṣegun Ajẹ) pẹlu Turari 2/ Itumọ ala ati ayẹwo Ifa 3/ Fi owo ranṣẹ tabi ki o wa ra lọdọ J. O. Shoyinka 6, Ojo Road Oduaborẹ Mushin.

## IDIJE! IDIJE!

Eyi ni lati fi kede fun gbogbo oloye ati ọmọran papa ọmọ Ibilẹ Yoruba ti o mọ owe yoruba pa, a nfẹ ogun (20) owe Eniti tirẹ ba dara ju yio gba pọun kan ṣilekan (£1 ; 1s) Ki se owe ti o wọpọ ni a nwi o, papa eyiti o ba jẹ ijilẹ owe ni a fẹ o.

Orukọ. ______________________

Ibugbe. ______________________

______________________

Iṣẹ ______________________

Ojo ori ______________________

Fi Owe tirẹ pẹlu Stamp Tọrọ (3d) ranṣẹ si:-

OLOTU IROHIN IMOLE
16, BAMGBOSE STREET LAGOS.

## Akiyesi Pataki

Eyi ni lati fi kede fun gbogbo ẹnyin Onkawe Irohin Imolẹ wipe, ẹnikẹni ti o ba ti kọ Owe Idije tirẹ, ti o si ti fi ranṣẹ, ti ko si fi Stamp tọrọ (3d Stamp) sinu rẹ, ki o tete kọ omiran ranṣẹ pẹlu Stamp tọrọ ki o si gẹ Idije sinu rẹ, nitori a ti fa ti akọko ya.

Fi owe tirẹ na ranṣẹ ki o le jẹ ẹbun Poun kan ṣilekan £1:1s ẹnikẹni ni o le kọ ọ, ko ba ṣe Ọmọde, Agba, Obirẹ, Alejo, ko buru Idije yi yio pari ni ipari oṣu yi tigbara Ọlọrun.

Olotu

OBERE LATI OJU EWE KEJI

ode ile ti ọkọ rẹ ri, lila ti o la ẹnu rẹ, nṣe lo daku bi wọn si ti sọpe egbawa ni aja ba gbe egungun lile ti Iyawo nle aja, lo ba yọ ṣubu, ni on na ba daku ti aja si sare ko si kanga.

Ọrọ na wa dabi ọrọ Tuletule ẹiyẹ to nṣu owo, borẹjẹborẹjẹ aiye to nsu wura, ṣe on lo da ija silẹ larin ọrẹ meji. Ṣe ọrọ lo nba mo ko mo ro wa, ọ r ẹ meji kan wa, ọkan ninu wọn ni ẹiyẹ kan, ti anpe ni borẹjẹbọ ẹjẹ. bi wọnba fun ẹiyẹ ni onjẹ lowurọ, bi oba ma ṣu yio ṣu owo ṣile rẹpẹtẹ bi oba di ọsan bi wọn ba fun ni ọka baba, yio tun ṣu W U R A R E P E T E ọka agbado ni ẹiyẹ borẹjẹborẹjẹ yi ma njẹ larọ. O wa di ọjọ kan, olowo ẹiyẹ yi fẹ lọ si idalẹ lo ba pe ọrẹ ri kọrọ wipe on fẹ lọ si idalẹ on si fẹ f ẹiyẹ on si ọdọ rẹ, o se alaiye fun wipe bi o ba fun ẹiyẹ na ni agbado jẹ daradara ni owurọ ti yiọ ba ṣu. owo ni yio ṣu, ati wipe ni ọsan ẹiyẹ yi yio ṣu ọpọlọpọ Wura bi oba le fun ni ọka baba daradara atipe awọu y i o wa pin owo na bi on ba de.

Nigbati ọkunrin Olowo ẹiyẹ yi lọ tan, ọrẹ rẹ bẹrẹ si bọ ni aboyo, ṣugbọn nigbati ẹiyẹ yi yio ṣu omi lasan lo nṣu repete, lọsan bakanna ni titi ti ọkunrin Olowo ẹiyẹ na fi de.

Dide ti Olowo ẹiyẹ yi de ile ọrẹ lo gba lọ lati ṣe abere wo wipe elo ni owo ati wura ti ẹiye on ti ṣu ki on to de, onitọhun si fesi wipe ẹiyẹ rẹ ko ṣu owo tabi wura rara ati wipe omi lasan ni ẹlẹgiri nṣu njọ, Olowo ẹiyẹ yi ko gba ọrẹ rẹ gbọ ni wọn ba ko ẹjọ odi ile Ọba. Nigbati wọn si de ile Ọba wọn niki olowo ẹiyẹ yi fun ni onjẹ, ṣugbọn ẹiyẹ ferẹ ma iti jeun tan ti o ti nṣu owo ati wura da silẹ repete, ni gbogbo awọn ti wọn wa nibẹ ba kigbe wipe borẹjẹborẹjẹ ni ẹiye yi. Jijade ti awọn ọrẹ meji yi si jade nile balẹ, ni wọn ba bẹrẹ ija ti wọn si lu ara wọn pa bamubamu.

Ẹyin ọjogbon onkawe Irohin Imọlẹ emi Olofofo Eko ẹniti iya fi ọja pọn dagba duro bayi. O tun di ọsẹ tombọ. Orisuruku ko nṣe temi ọmọkunrin duro bayi.

# Obirin Naijiria gba Oye O.B.E. ni Afin Buckingham



Pelu inu didun ni Iya-Afin Theodora Manuwa ti Eko ṣe fi Oye O.B.E. ti Ọbabinrin Gẹẹsi Elizabeth Keji fi da l'ọla han niwaju Afin Buckingham. Ọlọla Ọ m ọ b a Phillip ti iṣe ọkọ Ọbabirin Elizabeth ni o ṣe ile de aya rẹ ti o si gbe Oye O.B.E. le Iya-Afin Manuwa lọwọ ninu Agbala kan, ninu Afin Buckingham.

Iya-Afin Manuwa gba Oye O.B.E. fun iṣẹ ribiribi ti o nṣe ni Ilẹ Naijiria. E o ri ninu aworan yi pe o wọ Aṣọ Ibile, o s fi inu didun gbe Oye rẹ han lẹhin igbati o ti gba-a tan.


# MA SO IRETI NU RARA O

Bere awọn ojulowo egbogi Jamani ati orisirisi ilu miran wọnyi pataki ni fuu 'AJO' tabi 'ITỌJU' Obirin tabi Ọkunrin, ti ọkọ ati iyawo ti o daju. Meji iru wọn ko si ni gbogbo ṣọbu ni igboro ilu Eko.



Ekini :- Egbogi ti a npe ni ERMELINDA fun Obinrin oriṣi mẹta lo wa ninu Pali rẹ, o pa bambari fun ajo tabi idiwọ Adọta sile ( 50/-) ni owo pali kan jẹ, owo ọkọ rẹ 3/6d Ekeji :-Egbogi ti a npe ni SANURSEX fun obinrin Ṣilemejilelọgbọn pẹlu sisi (32/6) owo ọkọ 2/6d Ẹkẹta :- Egbogi ti a npe ni OPO JUVENCE fun obirin ( ojulowo Egbogi Awọn Faranse)

Ẹkẹrin :- Egbogi ti a npe ni DYNAMIREN fun obinrin Ṣilemẹrinla-abọ 14/6 owo ọkọ 2s Ẹkarun :-Egbogi ti a npe ni FANDORINE fun obinrin (Egbogi Faranse) Ṣilemẹrinla abọ (14/6 owo ọkọ 2s. Ẹkẹfa :- Egbogi ti a npe ni OSTỌRPIROS fun obinrin Ṣilemẹjọ abọ owo ọkọ ṣile kan Pere ( 1s)

OJULOWO EGBOGI FUN AJO ILERA TI ỌKUNRIN Ekini :- Egbogi ti a npe ni SANURSEX Ọgbọn ṣile (30s ) igo nla owo ọko 3s. Ekeji :-Egbogi ti a npe ni TESTONIC pawun kan (£1) igo kekere mẹwa abọ owo ọkọ 2s. Ẹkẹta :- Egbogi ti a npe ni DYNAMIREN Ṣilemejila-abọ (12s : 6d) owo ọkọ 2s.

Awọn egbogi wọnyi lagbara gidigidi wọn si n ṣ i ṣ ẹ ribiribi fun awọn ti wọn nlo wọn pẹlu, wọn ko dabi awọn egbogi Rọbirọbi ti wọn nta kakiri igboro iṣẹ wọn yatọ patapata, o si daju pẹlu.

Bere ojulowo egbogi omiran fun oriṣiriṣi amodi ti o ba fẹ ni ṣọbu:- Waterloo Medicine Stores 8, Palm Church Street P.O. Box 33 Lagos Nigeria Phone 22878

Ati pẹlu ni ṣobu arabinrin:- Mrs. C. O. Babajide, Near Health Office Ibadan ati ni Abimhola Medicine Stores B2a Okesha Street, Ilesha Bisale Medicine Stores AKIYESI - Ri daju gbangba wipe ṣọbu ti wọn nta lo ranṣẹ lọra, bi bẹ kọ awọn ẹlomiran yio fi eru lọta adamọdi tabi oriṣi omiran fun ọ o, maṣe gba r a r a .

